# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

709 TUESDAY, JUNE 2, 1964 (2D)


## Ọlọpa Mu Ẹlẹwọn Kan Ni Buka Ẹlẹmu

ONISHA:—gbogbo enia bẹrẹsi sere ọlọmọgbọmọ nigbati awọn ọlọpa wọ inu buka a ẹlẹmu kan nibiti gbogbo enia ti ngmu ẹmu t wọn si njẹwọ pẹlu ara wọn ti wọn si njẹwọ pẹlu ara wọn ti awọn ọlọpa sure wọle lojiji lati mu ọdaran kan Aleaze ti o si sa mọn wọn lọwọ ni asalẹ ọjọ Abameta ti ise Ogun jọosu karun ọdun yi.

Irohin awọn ọlọpa fi ye wa pe ninu osu kẹwa Ọdun ti o koja yi ni ọdarale na wẹwọn ọdun mẹdogun fun ẹsun ole jija ati ile fifọ sugbọn nigbati oluṭọn awọn ẹlẹwọn ko awọn ẹlẹwọn lọ sisẹ ni ode nigbati wọn o fi pari isẹ nwọn ni ọjọ na ni ọdaran na ba salọ larin awọn ẹlẹwọn yoku lati ọjọ ni awọn ọlọpa ti nwa ti wọn kọ si ti ri.

Ṣugbọn nigbati o di irọlẹ ọjọ kan awọn ọlọpanu ba wonu buka ẹmu kan ni Onisha ti nwọn ba ọdaran nu ni ibi ti o gbe yowo ẹmu ọlọpa ni on ba farabalẹ ki o ra ẹmu ti o fẹ ra tan, bi o sti mu tọbila meji ninu ẹmu na ni on ba ragabu ọdaran na sugbọn o yọ bọ lọwọ on

Lesẹkẹsẹ ni on ba sare tẹle ọdaran na ti o ti gbogbo buka ẹlẹmu na si daru sugbọn bi o ti ku diẹ ki ọdaran na sawọ inu igbo lọ ni awọn enia ti o wa nitosi base iranwọ nwọn si ba ọlọpa mu ọdara awọ ọlọpa mu odaran na si itimọle ni Tesan asiropẹ yio fa rahan niwaju adajọni owurọ yi bi wọn bati se ejọ na o ma gbo ninu irohin wa.

## Ibiti A Ni Gbegbe O Ma Gbe Ibẹ Ni Gbe, Ibiti A Ni Tẹtẹ O Ma Tẹ Ibẹ Ni Tẹ

# DOKITA OKPARA ṢE BẸ Ẹ, O DE IPINLẸ IWỌ-ORUN!

NSUKKA:— Sangba fọ! Ọrọ bẹhin yọ!! kaluku mọ iwọn ararẹ nigbati Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe, Olori Apapọ Ijọba Naijiria da esi waya ti Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pada si ni Ọsan ana Ọjọ Aje ti iṣe Ọjọ kini Oṣu yi pe, ẹnikẹni ni Orilẹ ede yi lo ni anfani lati rin si ibiti o ba wu Oluwarẹ laisi ohunti o le ṣe idiwọ tabi idena iru ẹni bẹ.

Gẹgẹbi irohin ti o de si Ile iṣẹ wa ni Ọsan ana. a gbọ wipe Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi, lo tẹ waya ranṣẹ si Ọlọla Azikiwe pe, ki o lo aiye rẹ gẹgẹbi Olori Apapọ Ijọba ẹniti iṣe baba gbogbo ilu ati ẹniti idi ati aṣẹ Ijọba Orilẹ ede yi wa lọwọ rẹ lati da Dokita Okpara duro ki o maṣe ṣe ibẹwo si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, eyiti Dokita Okpara fẹ bẹrẹ ni owurọ yi.

Ninu waya na, Ọlọla Ọdẹlẹyẹ tun ṣe alaye pe, awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti fi ifẹ Ọkan wọn han gbogbo aiye pe, ki Okpara da ibẹwo rẹ duro si Ipinlẹ na, ki o maṣe wa.

Ni ipari, Ọlọla Ọdẹlẹyẹ wa rọ ọlọla Azikiwe lati da Okpara duro ninu irinajo ti o fẹ rin si Ipinlẹ na gẹgẹbi ifẹ ọkan awọn Ọba ati awọn enia Ipinlẹ na.



**Ọlọla Nnamidi Azikiwe**
OLORI APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA

Ṣugbọn ninu esi ọrọ rẹ si waya ti Ọdẹlẹyẹ si i ni Ibadan ni owurọ ana, Ọlọla Dokita Nnambi Azikiwe wa bere pe, kini iṣe ti awọn Ọba fi sọpe Alakoso Ijọba Ipinlẹ kan ko gbọdọ rin si ibiti o ba wa ni Ipinlẹ kan ni orilẹ ede yi? Tabi ki iṣe ọkanna ni gbogbo wa mọ?

Ọlọla Azikiwe ni, gẹgẹbi imọran ti Ọlọla Ọdẹlẹyẹ gba on lati lo aye on gẹgẹbi olori Apapọ Ijọba, ṣugbọn o ṣe alaye pe, on ko tiṣe ohunkohun si ọrọ na nisisiyi nitoripe, ohun ti nrunninu igbẹ ko ti jana

O wa pari ọrọ rẹ pe ọrọ na ko ti de aye ti o yẹ fun on lati lo ida ati aṣẹ Ijọba ti o wa lọwọ on, nigbati asiko ba to, ara ile koni sọ fun ara oko, ẹnikan koni sọ fun ẹnikeji, gbogbo enia ni yio mọ karikari

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe lati bi ọjọ mẹta ni ati ngburo pe, Dokita Michael Okpara Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Nai-

WỌ OJU EWE KẸFA

## ỌRỌ OLOTU

### Enyin Alakoso Ijọba, E Dakẹ Ni? (2)

Gẹgẹbi alaye ti a ṣe fun ẹnyin onkawe wa lana ninu iwe wa nipa ibẹwo ti Dọkita Michael Okpara, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Alakukọ fẹ bẹrẹ si Ipinle Iwọ Orun Naijiria ni owurọ yi eyiti a ro pe yio jẹ anfani fun awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ati Dẹmọ pẹlu gbogbo awọn ara ilu ki nwọn maṣe jẹki ija tabi rogbodiyan o ṣẹlẹ larin awọn ẹgbẹ mejeji, on ta ni a tun fẹ ṣe alaye diẹ le lori ui owurọ yi,

Lati bi ọsẹ kan sẹhin ni awọn ọmọ ẹgbẹ mejeji ti nṣe iteri si ara wọn pẹlu "ihalẹ" ohunti awọn o se si ara wọn bi ẹnikeji ko ba da ohun ti o fẹ ṣe duro ti awọn ọmọ ẹhin oni tọh n si nsọ pe "Maa bọ, ko ṣewu loko a fi huhu-aparo"

Ni tootọ, Dokita Okpara nlọ si Ibadan ni owurọ yi lati lọ ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ, ki o si fi oju ri gbogbo wọn. Atiro ni on jẹri ọmọ on, ko jẹ ra bata ranṣẹ si on. Ọrọ ija tabi rogbodiyan ki iṣe on ajeji si awọn ara Ibadan, Bi o ba di ọrọ ija, awọn ara Ibadan ko bẹru aiya ko fo wọn bẹ si ni ko si ominu fun wọn pẹlu, nitoripe ki iṣe ajoji si wọn.

Njẹ Ilu Ibadan ko ha ni jẹ oju ọgbagadi fun awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ati Alakukọ pẹlu awọn Ọlọpa ni owurọ yi bayi? Njẹ o ha yẹ ki Dokita Okpara fi opin si irinajo rẹ si Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria gẹgẹbi awọn "Janduku-alajagbila ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti ṣe da imoran?

Ti ẹ ba wo oju ewe Iwe kini wa owurọ ana, a ṣe irohin kan sibẹ nibiti awọn Ọlọpa ti ua Alhaji H. P. Adebọla ati Michael Imoudu ni asasifilasọnu ti gbogbo enia si ri ẹjẹ ti o nsan jade bi omi-odo, awọn enia diẹ wa ni Ile-iwosan nisisiyi.

Awọn Ọba diẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti kọ iwe abẹle si Dokita Okpara pe, ki o ma ṣe wa si Ipinlẹ Iwọ-Orun ni asiko yi, nitoripe, awọn ko fẹ ki ẹnikẹni ni Ipinlẹ yi fi oju ri ẹjẹ ọmọ enia.

Awa Oniwe IROHIN IMỌLẸ ri i daju pe, o yẹ ki awọn Ọba o tun sọ ọrọ yi fun gbogbo awọn enia ti o wa ni Ipinlẹ na,

WỌ OJU EWE KẸFA

# Atunṣe Fun Ilẹ Yoruba

## Lati Ọwọ S. O. Jaiye Eko

Lọni yi, o dabi ẹnipe Yoruba di ẹni ıręsilę larin ilę Naijiria ohun to ba jọ ohun ni a fi we ohun na, Bi ẹnikan ba wa ti o nwo ọta rę niwaju ti awọn to wa yi ka ba si npolowo ẹni na ti ko ba sọra laipę ẹni na fi a nyin ti a si npolowo rę ti ko ba mura giri ki on papa mọ ibi ti agbara on wa ko ni pę di ẹni ẹhin. Idi yi ni pe on ko le ri ara rę bi o ti tọ ti o si yę.

Lọna kini gbogbo e n i a pataki ṣe Yoruba lo fęrę ma sin itọ si enia l a r a wipe awa bi Yoruba ki işe ototọ Ati pe ko si ohun ti enia le se ki awa Yoruba ma dalę oluwa rę fun ifę owo

Ẹlomi tilę nsọ leti mi pe "Ki a ni pe Yoruba "ọęni otitọ mọ." Gbogbo ọrọ to ba tęle e otubantę irọ runfun gboo ni awọn ọrọ to tęle e

Njẹ mo ba le da awọn iru enia bę bę ę lẹbi? Awa papa to mọ ara wa bi ẹni mọ owo ri gbogbo awọn alebu ara wa laijẹ ki ara ita sọ fun wa. Gęgębi mo ti wi ṣaju g b o g b o a w ọ n lo nda ẹbi fun ilę Yoruba. Bęni ẹnikan io eponri ni ilu ti a fi npe na ni ilu aponri

IWA AMULUMALA

Ẹkọ ajeji işelu ti ta epo si ara elara iwa Eyi ni pe iwa amulumala ilu şişe mu iwa ikorira wa si arin ilę ilu ati orilę ede wa

Niti pe ọmọde ọkunrin to wa rinu ẹgbę Afenifęre ko tun fi ifę han si ẹgbę Alakukọ

To bę ge iwa yi ni a nhu larin ara wa ti a ko ranti bi awọn baba wa ti nko ilu wọn jọ nigbana iwa şę eyi nigbati aiye wa ni jo jolo. Ohun gbogbo ko ribę nigbana.

Iwa ilu şişe ko mu rogbodiyan wọ ilu rara tabi ki ija ikorira ara ẹni wa. Fun idi eyi ni a w ọ n ma npe lowe tabi sọ mọ ọrọ pe aşiwere nija ija ilu kan Tabi fun ẹnikan lati gbe ọrọ ilu kari bi ẹnipe ko si ẹlomiran mọ larin ilu pęlu rę.

Ambọtori ki a şęşę ma korira ẹnibi ẹnipe ki iku yọ si ki o si ma gbeni lo bi agutan fun pipa.

Bi mo ti jọko ti mo nronu lori awọn ohun ibajẹ to wa larin awa Yoruba, Mo wa ri kedere pe a w a ęran ati ma tan ara wa. A ki jade otọ si ara wa.

Bęni laişepe afi otitọ ba ara ẹni lo ko si ohuu ti a le ma jade fun ohun rere kan. Bi alagbaja ba jẹ iyekan wa, ti o ni i w a ti o buru dipo ti a baja lori iwa yi titi on yio fi ronupiwada fun rere awa ko ni jẹwọ iwa rę bęni ipakọ onipakọ ni a nri. Ẹni ẹleni lo nri ti wa.

Bęni Ọ'ọrun da o h u n gbogbo sinu a i y e yi Ti Yoruba yo ba tun arin ile rę şę. A ni lati ni igboya lati sọ alebu wa fun ara wa. Eyi ni pe ki awọn ọmọ Yoruba n lati ma gbidanwo lati ma sọ abę n i i. o

Bi o tilę jẹ pe ki şe aşa Yoruba lati ma şe ojugangan si ẹniti o ba wa niwaju rę. Awọn ẹlomi ninu ẹya ile wa ko ka'si iwora lati so abę nibę niko nigbati o jẹ wipe o npe ọrọ sọ fun awọn to wa yi ka tabi awọn to w a niwaju nwọn.

Emi papa ko da awọn enia mi "Yoruba" lẹbi şugbọn o yẹ ki ala wa fun ni lati mọ igbati o yẹ ki a sọ otọ fun ara wa.

Aile jade koro si de fun ni Idi rę ji gbogbo iwa



Ọgẹni S. O. Jaiye

eri pepepe fi sọ aso iwa wa di pata.

Laipę yi mo ba ọdọmọ dekunrin kan sọrọ wipe ki o ra iwe orire ti Iwọ Orun. Mo so fun pe ki ora boya eri re lo wọ agbe if, fijẹ. Bi o tilę jẹ w i p e akowe kan ni ọmọkunrin yi jẹ şugbọn esi rę si imọran mi ya mi lenu pupo. O wipe emi ko le ta orire ti I w ọ Orun nitori bi mo b a j ę awọn Yoruba kọni fun mi lowo na.

Nitori awọn le lo ogun lati yi nọmla m pada k i o mọşe jẹ temi mọ. Erin fa mi fun iwa ọpe ọmọkunrin yi şugbọn ngko le dalębi fun iru iwa ifunra to ni lori Ilę Yoruba

Nitori biiya aisọtọ awọn aşaju wa ba gbeni wọle tan kekeke a ma gun ori ẹni

Şugbọn ni idakeji ọmọde yi ro wipe Yoruba kun fun gbogbo agbara gbogbo ki ma tan ara wa jẹ gbogbo awọn ẹya miran to wa larin wa ni o ni iwa ifuura si wa pupọ.

Kosi idi miran to mu ifunra wa bi ko şe i w u ekuteie to jẹ tan to bęrę si fęni ara. Ti ao ba ma atunpad iwa ododo wa si arin wa.

Gbogbo iwa alebu ti a ti sọ fun ara ẹnil ojojumọ ni lati yi pada. Ki a si bęrę si fi iwa atijọ kọ a w ọ n ọmọ wa

Laiye lailai awọn ni a ki mo ẹkọ ọmọ ẹni tan ki a tun mọ ale r . Şugbọn li ode oni awọn aşaju wa mọ ọkọ ati ale ọmọ nwọn tan ti nwọn tun sọ f u n ọkọ ọmọ wọn pe ẹgbọn iyawo rę ki ę.

Iwọsi ọkọ tun dọbalę fun ale aya rę fun aimọ, Nitori iwa aisododo to wa larin wa loni.

ORITA MẸRIN

Li oni, orilę Yoruba wa lorita mẹrin aiye Ọna daru ko si amọna larin n w ọ n nitori ifę owo ati aisododo Ohun to ku ni Ipinu lati yan ọna kan ti yio ma gba lọ si ọna ajo rę.

Ọpọ ni ẹri nigbati ọ n a poruru bęni a w ọ n ti ko mọna jade lati fi ọna kan han alaimọna nihin ni ọrọ wa.

Ohun to dara julọ fun wa bi Ọmọ Enia ni pe ki a duro jẹ lati ma fi suru yan ju ọna rę. Laipę kuku to bo ọna mọlę yo fo lọ yanyan

Oluwa ti nfi ọna han ni ki o mọsalai fi ọna h a n gbogbo ilę wa yi. Ẹjẹ ki ama te si waju ninu ọ n a rere gbogbo Ki oga ba le jẹ ti wa o,

O digba o


# PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rę ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu bun nkan bi ọdun kan tabi jubę lo awọn egbogi rọbirọfi ko le se iwosan rę rara, ma fi owo rę şe Ofo mo

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni P O R A L ojulowo hanunhah n, atamatase egbogi fun, Ikọ here Ikọ otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaaya, Ikọ lile. Ikọ, ti o ma mu enia tu kęlębę nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pęlu

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wọ Iwọ na yio ri fyatọ ninu ara rę ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rę ti o m a nho yio duro "IKỌ" rę yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pęlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orişirişi Egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
Phone:- 2278 (Ọj. Ita Faji)
8, Palmchurch Street, Lagos Nigeria



E ma a Ka Irohin Imọlẹ lojojumọ

# IWE SI OLOTU

## Awọn Iganmuṣe Pọ Ni Ibadan

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi ni aye ninu iwe rẹ ti nkọwa ni ọgbọn aye lati kesi Ijọba Ibilẹ Ibadan ki nwọn ran wa lọwọ lati le awọn ti o nta tẹrẹ ojukoju kuro ni Ilu Ibadan, nitoripe alejo ti nwọ Ibadan lojumọ ti pọju, awọn alejo yi si ni nwọn umu nigan.

Ti enia ba ti yọ ni ọkan ni nwọn yio ti pe, awọn a ni ki o wa ra ọkan ninu iwe ti nwọn we kaduru, nwọn nta omiran ni ṣile kọọkan, omiran ṣile meji, bi oluwarẹ ba ra tan ti o ba tuwo ko ni ba nkankan ninu rẹ, wọn yio tun ma ṣe yẹyẹ.

Bi mo ti nlọ ni Opopo Agọdi ni ẹba ọja-Oje ni Ọgbẹni kan ba gbe panti rẹ kalẹ ti o nlu agogo pe rara ! Igan-mu ṣe mu owo wa ki o wa sori rẹ gbogbo wa ya si ọdọ rẹ o fun ẹnikọọkan wa ni pali lẹhinna o gba pada o sọ pe ki a mu iwe ti o di, a si mu ọkọ kan bi o ti ja ti ẹnikan ponun marun lori ninu rẹ, o ni ki o mu ponun kan wa ki o maa ko owo na lọ ara wa bu m ọ aṣọ

Bi Ọkun in yi ti fun ni ponun kan ti o gba ponun marun lọgan owo na poora, iyoku di iregbe bẹni ẹniti o ri ago isomọwọ ninu tirẹ, o gba ponun kan ago tun parẹ, ni nwọn ba da ija silẹ o wa di bi o lọ ki o ya fun mi Olotu ẹ ku iṣẹ o.

Emi ni
*Sunmonu*
ỌFFA—IBADAN.

tun jẹ ki ilu na dabi eyiti o wu enia lati mọ ka.

Loju temi, nko fẹ ki itan na tun mọ lailai mo ki onitan na ku iṣẹ.

Ẹ ṣe pupọ Olotu Ajinde ara yio mọ *jẹ* o,

Emi ni
J. A. Atanda
ILESHA,

## Ẹ Ṣanu fun Awọn Alaini

Nba sọpẹ bi ẹ ba le gba mi ni aye ninu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi awọn olowo ati ọlọla wa ki nwọn ran wa lọwọ awọn alaini pọ ni ilẹ wa. Ofin Ọlọrun ni ki a gbe ọmọnikeji wa ga ju bi a ba ti gbe ara wa ga lọ.

Ẹ jẹ ki a ran awọn aburo, ẹgbọn ati ọmọ aburo wa lọwọ ẹ jẹ ki a tun tọju awọn ọmọ ilu wa.

Iwa ti lagbaja ko kan mi ko dara, ẹ jẹki a jọwọ kuro ninu iwa kẹnimani o yẹkiamaran awọn ọdọ wa ti ko ni lọwọ, ki a fun wọn ni ẹkọ ọfẹ.

Ọlọrun ti ṣe wa ni olowo ko sa fẹran wa ju awọn yoku lọ, bẹ ni iwa wa kọ lo dara, bi a ba si ku loni, iṣẹ rere ti a ṣe ni awọn enia yio ma rohin, ẹ

Emi ni
G. Alawode
OGBOMOSHỌ.

## Ẹ fi eto si iki-irun awẹ

Olotu, ẹ dakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati ba gbogbo Musulumi sọrọ atata, nitoripe o jẹ nkan ti ma dun wa lọkan nigbati ẹsin wa ko ba ba ara wọn mu, ni ọjọ ti mo ti daiye emi ko ti gbọ pe gbogbo Musulumi jakejado ilẹ Naijiria kirun aawẹ papọ tabi ni ọjọ kanna ri a fi ṣegeṣege.

Awọn orogun wa ninu ẹsin asi ko kanna ni gbogbo ẹsin wọn nbọ si ọdun ti nwọn nṣe iranti ọjọ ti nwọn kan Jesu Kristi Oluwa mọgi ọjọ kanna ni kakiri gbogbo aiye.

Bi nwọn nṣe ọdun Ajinde Oluwa ko yatọ rara ọjọ kanna ni kakiri agbaiye o yẹ ki awa na ni Igbimọ ti yio ma ṣẹnu fun wa Igbimọ ti yio ma ṣe eto awọn asiko ti ao ma ṣe ọdun ti awa na si.

O yẹ ki o jẹ wipe asiko kanna ni ao ma a ṣe ọdun Aawẹ ni ilẹ wa Naijiria, ki a ṣe ọdun itunu aawẹ papọ ko di orişirişi ẹsin wa lọwọ rara.

Ẹ jọwọ ẹ finu-konu, ki ẹ si. pamọpọ, ki awa na le ni asiko, kanna lati ma ṣe ayẹyẹ ẹsin wa Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
S A Alimi
IBADAN.

## Ṣhoyinka Ọṣe-we Tan !

Ko ṣe pe, a nṣe ẹnu lẹṣọ ni ti aba nsọ wipe itan yi ko ni ẹgbẹ ninu awọn arosọ itan ti awọn Yoruba ma nsọ mo niran igbati mo wa loko ti awọn baba wa ma sọ itan fun omiran a ma ba wa lenu omiran asi tun ma pawa lẹrin, ṣugbọn eyi yato.

Nitotọ aka Ogboju Ọdẹ ninu igbo Irunmọlẹ ati awọn yoku aka



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

Itan Koru ati Ọpalaba ṣugbọn itan Aj'ran ilu awọn oku ta gbogbo wọn yọ ẹgan ni bẹ, ọlọmọ kan kuro ni kini o tilẹ bi.

A ngbadun itan na ni bi igba ti enia ba ngbadun iyawo aṣẹṣẹ gbe paapa aworan ilu Ajiran na dara gan ni ilu ti nwọn fi egungun ori oku yi ilu na ka iyẹn


# MODUPE PRINTNG PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING
*For Your Next Printing Jobs:*

Just Call 21985 — Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.

# SEDO — PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba, A'efọ, Egbo esẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi eda-rin egbo, ekusẹ tabi ekusẹ tabi lapalapa, Ela tabi ara sisu, Akọ inarun ati orişirişi orun "Ara" miran gbogbo.



Gbiyanju lati dan egbogi titun awọn ara Ilu Tatanbu bulu ṣe ti nwọn npe ni "PAYAL" wo larin ọjọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran nelu Egbogi ipara yi ki ṣe awọn rọl irọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowo egbogi arun arun ara baunhaun ti ko si şişẹ ye meji ninu eleyi si yatọ patapata si awọn ẹgẹrẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri igboro ati ni agbereko gbogbo pelu. Orisi meji re lo wa Kekere ati Nla.

Bere egbegi Ajẹbidan SEDO PAYAL yi ni ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
Phone:- 2278 (Oj. Lagos Nigeria
8, Palmchurch Street, Ita Faji)

PILENAB MIXTURE.
Egboigi olomi dara julọ fun awọn omode ti jẹdijẹdi bi ako ghonse dede ba nyo lenu bere ro ni
WATERLOO MEDICINE STREES
'AFAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# Ọlukọ Kan Gbe Bata Ọlọpa

IKẸJA:— Oju gba gbogbo awọn enia ti o wa ninu ile kekere ti o wa ni Ikeja ti nigbati abanirojọ fun Ijọba nka ẹsun ole jija iwe yivi paapa pe, Ọgbẹni Josaiah Adenka ẹsin ole jija iwe yivi paapa pe, Ọgbẹni Josaiah Adesida Ọmọ ọgbọn ji bata Ọlọpa gbe. Gbogbo ero ilesida Ọmọ ọgbọn ji bata Ọlọpa gbe. Gbogbo ero ile-ẹjọ na lo woke ti nwọn tun wolẹ wọn l'fẹun abi edi ni eleyi ti Odidi Olukọ fi lọ ji bata Ọlọpa elemiran ni elo ni owo bata to wa jẹ wipe bata Ọlọpa ni Ọdaran na wale jigbe.

Ẹ jọ ti abanirojọ ijọba ro mọ Ọgbẹni Joseph Adesida lẹẹẹ ni pe larin oṣu kọkanla Ọdun ti o kọja ni Ọgbẹni Adesida wa lati Akurẹ lati se idanwo ni o ba de si ile Ọgbẹni John Falade ti o nṣe iṣẹ Ọlọpa. Lati Ado-Ekiti ni Ọgbẹni Adesida ti wa se idanwo ni agbegbe Eko ti o si de sile ọrẹ rẹ bi Ọgbẹni Falade ti jade nile tan ni alejo yi ba ko ẹru ti o to pọnun mẹtala ati sile marun ti o si tun ji bata ti iye owo rẹ jẹ pọnun mẹji-abọ lo ba fi ẹsẹ fẹ ẹ.

Nigbati Ọdaran na gba pe on jẹbi ni adajọ Ọgbẹni I. A. Ọnalaja ni ti nwọn kọkọ nu ni atorin mejila na ki o wa ṣe idajọ kun pe ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹsan pere

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS[(Jan 22-Feb 20) Lo ọgbọn ori rẹ lati ṣe iṣẹ kan loni, Bi o ba ngbero lati ṣe inawo kan kiakia maṣe yara ṣe pupọ, Nitoripe alaigbọran ni awọn ọrẹ ti o ni, yio jẹki irin ajo rẹ yẹ.

PISCES (Feb 21-Mar 20)' Ma yọ ki inu rẹ si ma dun toripe awọn orisa yio ṣeran lọwọ fun ọ pupọ, Ọrọ kan wa nilẹ fun ọ ti o ni lati yanju aya fi bi o ba yanju rẹ fun ra rẹ.

ARIES (Mar 21-April 20) Orisa yio jẹki ara rẹ ya kankan loni. Bi o ba daniyan lati fi iṣẹ rẹ silẹ ki o si lọ wa omiran o daju pe iwọ yio riṣe.

TAURUS (April 21-May 20) Gẹgẹbi orisa ti wa ni alati lẹhin fun ọ o daju wipe iwọ yio bori iṣoro gbogbo Aibamọ bi o ba pade alatako maṣe binu pupọ.

GEMIM (May 21-June 21) Ṣọra loni, nitoripe o han gbangba wipe ole padanu owo loni yi na ohun ti o ba ni ṣa pati sẹgbẹ kan titi iwọ yio fi ri akoko lati ṣe inawo na.

CANCER (June 22-July 23) Ṣe jẹjẹ loni iwọ yio si ri iranlọwọ awọn orisa lati fo gedegbe ninu awọn iṣoro gbogbo. Mase ro ara rẹ pin wipe niẹ ngo le se nkan yi.

LEO (July 24-Aug 22) Gbogbo ero ti yio ma wa si ọkan rẹ loni yio jẹ ero rere ki o si ma ro ori wo daradara ki o to ṣe nkan pẹlu ọgbọn ati laakaye iwọ o bori gbogbo isoro iwaju rẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ohun ti o yẹ ọ loni ni wipe maṣe wiregbe pupọ ma si se ba ẹnikan jiyan, ṣọra ki o ma se ṣẹ ẹniti o fẹran rẹ ọrọ rẹ ko ni ta niwaju awọn obinrin loni.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Ṣọra rẹ lọpọlọpọ ki o ma ba da si ara rẹ lọrun nipa biba obinrin kan ta lẹnu iṣẹ, tobẹ ti ara rẹ yio gbẹkan, iwọ o si gbagbe pe lẹnu iṣẹ li o wa, maṣe jẹki igbagbe sun ọ debẹ.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Ronu rẹ wo daradara ki o to ti ibiṣẹ kan bọ si ekeji, maṣe jẹki ibinu sun ọ la ti binu si ẹsiṣẹ ẹgbẹ rẹ, ọjọ oni dara fun ọ lati ri owo.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22) O yẹ ki o kọkọ ma dan nkan wo ki o to ṣe ki o ba le jẹ ẹkọ fun ọ, ṣọra rẹ nitori gbogbo ara yio ma ro ọ.

CAPRICORN Dec 23 - Jan 21) Ohun to nṣe ọ ni ara riro nfọ riro lọ fi ara han onişegun rẹ, fi iṣẹ silẹ ki o si lọ simi fun igba diẹ.

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti a si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan Erok wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo

## Apejuwe Ile Iṣẹ Wa

Ẹ wọ Bọọsi ti o nlọsi Lawanson ni Yab 3d pere ti oba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igb Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ila na Yanrin titẹ ati Etutu Şişẹ | 4/- |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 7/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 10/6d |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 1/- |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | |

## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a pe ni:

### 'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹra'u tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba i lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ehin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisun be nyọ ọ lẹnu ... lere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STOE
Tinubu Square Lagos.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# Itan Işẹdalẹ Ilu Modakẹkẹ

(Lati Ọwọ:- MUDASIRU BABAYODE ỌDỌFIN OLOGUN IKARẸ

MODAKẸKẸ ṢẸGUN OKE IGBO ATI IFẸ PAPỌ

Lẹhin ọgbọn ọdun (30 years) awọn ara Oke-Igbo wa ran Ifẹ lọwọ wọn si tun gbogun ti Modakẹkẹ şẹgun Ifẹ lasiko na.

Nigbati awọn Modakẹkẹ ri i pe awọn tun şẹgun wọn, ni nwọn wa nta wọn lẹru, nigbati ara awọn Ifẹ ko gbas mọ, ni nwọn ba tuka lọ si Oke-Igbo, Isọya ati bẹbẹ lọ.

ALAFIN ATIBA SỌ MODAKẸKẸ DI OMINIRA NI ỌDUN 1854

Nibọ ni wọn wa titi fi di ọdun 1854, ni bati Alafin Atiba wi fun Ogunmọla Ibadan pe ki o mu Ifẹ pada o si şe bẹẹ. Ifẹ se ileri pe gbogbo nkan awọn ti o wa lọwọ Modakẹkẹ, awọn ko ni bere, şugbọn lẹhinti wọn pada de ni awọn iyawo wọn pada wa ba wọn.

ILU MODAKẸKẸ NI ỌDUN 1909

Lati igbana ni Modakẹkẹ ti di ominira (Independent titi fi di ọdun 1909 ti ilu Modakẹkẹ tu.

Modakẹkẹ pẹlu Ifẹ si jọ ngbe pọ to tẹ ti nwọn nfẹ ọmọ ara wọn ni iyawo.

MODAKẸKE ŞẸGUN IFẸ NIGBA OGUN EKITI-PARAPỌ

Lẹhin eyi ni ogun Ekiti-Parapọ bẹrẹ, Ifẹ kọkọ nigbija Ibadan, şugbọn nigba ti Arẹ Olubadan igbana fẹ fi Ayikiti jẹ Ọni fun awọn ara Ifẹ pẹlu ipa wọn fi Ibadan silẹ nwọn si ngbija Ekiti-Parapọ.

Nigbana ni ifẹ ati Modakẹkẹ tun pade ija, Modakẹkẹ si tun şẹgun Ifẹ.

IJẸSHA, EKITI ATI IJẸBU RAN IFẸ LỌWỌ

Nigbana ni Iẹsha, Ekiti ati Ijẹbu wa oran Ifẹ lọwọ awọn ara Ibadan na si oran Modakẹkẹ lọwọ, ogun yi le fun Modakẹkẹ şugbọn nwọn mba ija na lo titi ti ija na fi pari ni 1888.

Awọn Balẹ ti nwọn jẹ ni 1909 titi di 1918 ni wọnyi:- Wingbolu, Fatunmi ọjo Akitikori ọmọ Aserawọ, Kutanbi ọmọ Wingbolu, Ogunwọle ati Akinsanya.

Ni aiye Akinsanya ni Modakẹkẹ to gẹgẹbi adehun ti nwọn şe pe bi Modakẹkẹ ko ba fẹ wa ni abẹ Ifẹ nwọn nilati kuro ni ilu wọn.

Awọn Ifẹ papa ko fẹ ki Modakẹkẹ kuro mọ ni akoko ti a nwi yi nitoripe, nwọn ti wọ inu ara wọn.

Şugbọn Ọni igbana ti anpe ni Adenẹkan ni o mura si ọrọ a lọdọ awọn Ijọba ti nwọn fimu Balogun ati Ọtun rẹ lọ si Ibadan,

Lakoko yi ni Ifẹ wa nyọ Modakẹkẹ lẹnu to bẹẹ ti nwọn ko gbọdọ ri wọn ni igboro Ifẹ.

AJẸLẸ FUN IFẸ L'AŞẸ PE KI O LE MODAKẸKẸ JADE

Ajẹlẹ Oyinbo tiowa ni Ifẹ nigbana paapa fi ọwọ si i pe, ki awọn Ifẹ ma a ti iya jẹ ẹnikẹni ninu awọn Modakẹkẹ ti wọn, ba ti fi oju ri,

MODAKẸKẸ TUKALỌ NI ỌDUN 1909

Nigbati awọn ara Modakẹkẹ ri i pe iya na pọ, ni nwọn ba fi ilu silẹ ni ọdun 1909: apakan lọ si Ọwu Ipole, Gbọngan, Ẹdun—Abọn Ẹdẹ, şugbọn pupọ ninu wọn ba Akinsanya Balẹ igbana lọ si Ọdẹ-Omu, nitoripe nibẹ ni Ibadan ti pese silẹ fun wọn. Ohun ti o fa a ti wọn fi npe ibẹ ni Ọdẹ-Omu nipe:- Odo kan wa nibẹ ti awọn ara ilu Modakẹkẹ joko ti, şugbọn Odo na ki i ni omi ninu nigba ẹrun ti awọn ọdẹ le ma mu, ni wọn ba fi npe ibẹ ni "Ọdẹ omu"

ỌBA ADERẸMI KO FẸ IYỌNU

Lẹhin eyi ni a tun Modakẹkẹ tẹ ti o si wa ni abẹ ifẹ. Nwọn ri iyọnu pupọ labẹ Ifẹ nipa isakọlẹ, ọrọ na di ẹjọ ilu Oyinbo ki o to pari Ọba Aderẹmi ko fẹ iyọnu.

fun Modakẹkẹ nitori ti o jẹ enia rere ati pe ọmọ Ọyọ ni iya rẹ

Şugbọn kogbona ko tutu ni ọrọ Ifẹ ati Modakẹkẹ titi di Ọdun 1952, to bẹẹ ti ọrọ wọn na fi jade ninu iwe Irohin kan ti a npe ni(West Africa Vanguard) ni 27th June 1952.

Oyesiji ti o jẹ Balẹ Modakẹkẹ ni asiko igba na ko mọ okan kan nipa ọrọ 1952 yi nitoripe ni Ọdun 1951 ni ofi aiye silẹ.

Gẹgẹbi nwọn ti sọ fun wa ninu oşu kejila ni pe o ku ni December, 7th 1951. Lẹhin rẹ ni Oyeyẹmi jẹ oye


## BI O BA NI Iwe—Tite

*FUN*

**Lilo nibi Işẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE–IŞẸ–ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkansoso k o ri iyatọ*



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ẹ şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa la ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn alera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Şọbu:a

Waterool Medicine Store
8, Palm Church Street, Lago-
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 709 TUESDAY JUNE 2, 1964 (2D

## Ẹniti oji Basikulu Gbe Wẹwọn Ọdun Kan

ILESHA:- Oju gba gbogbo enia ti fun ọdaran kan, Festus Oloyede, ẹni ọdun mẹrinlelogun ti awọn ọlọpa mu wa sinu ile Ijọba Ibilẹ Ilesha ni ọjọ Abamẹta ti iṣẹ ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi fun ẹsun ole jija, ati ile fifọ.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na sẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, ẹpọlọpọ enia ni adugbo na ni nwọn ti wa rsọ ni Tesan pe awọn ji basikulu awon gbe ti awọn ọlọpa kẹ si mọ iru awọn enia ti o nṣe bẹ larin ilu.

Ṣugbọn ninu oṣu ti o kọja yi, ni ọdaran na lọ si ile iṣẹ waya ati ifiwe ranṣẹ pe on fẹ tẹ waya. Ṣugbọn nibiti o duro si niwaju awọn oṣiṣẹ ni o gbe fi ọwọ fa ontẹ Ijọba (Stamps) mẹrindinladọta, ati kalamu ti akọwe na fi nkọwe lẹnu iṣẹ rẹ ti iye owo gbogbo awọn ọja na jẹ, pọnun mẹdọgbọn sile mẹfa kobọ mẹwa (£25, 6s.10d).

Bi ọdaran na ti ji awọn ontẹ Ijọba na tan ni o ba sare jade, o sare lọ gun basikulu rẹ, ni awọn enia ti o nṣe akiyesi gbogbo iṣẹ ti o ṣe bajẹ fun ọgbẹni na Akin Adejunwọn ti o nta awọn ontẹ ninu ile iṣẹ na.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia ti o wa ni tosi ba tete sare lọ ba ọdaran na, nwọn si mu wa si Tesan ọlọpa, nigbati o de Tesan gbogbo ontẹ Ijọba ati kalamu akọwe na ni awọn ba ninu apo sokoto rẹ nigbati awọn si wo kẹkẹ ti o gun wọn ri wipe ara awọn kẹkẹ ti nwọn ji gbe ti awọn ti nwa ni kẹkẹ na.

Nigbati ọdaran na ro ẹjọ, ti o si gbọ pe on jẹbi ẹsun ni adajọ ba paṣẹ pe ki o lọ fi ẹwọn ọdun kan jura.

# Okpara Lọ Si Ipinlẹ Iwọ Orun

yio ri ṣe itẹwo awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ Alakukọ.

Ṣugbọn nigbati irinajo rẹ ku bi ọsẹ kan ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ṣe ofin pe ko gbọdọ ṣi ipade gbangba ati ipade iwọde yika Ipinlẹ

Lẹhin na ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ tun sọ fun Okpara pe ko gbọdọ wa si

## ỌRỌ OLOTU

### LATI OJU EWE KINI

ki iṣe Ọlọla Dokita Okpara nikan lo yẹ ki nwọn sọ ọrọ na fun.

Ṣugbọn yio tun dara lọpọlọpọ bi Dokita Okpara ba ti wọ inu igboro ilu Ibadan ni owurọ yi ki o kọkọ lọ taara si ile Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria, ki awọn mejeji o jijọ ki ara wọn gẹgẹbi Alakoso Ijọba si Ijọba.

Bi o ba ṣeeṣe pẹlu, ki awọn mejeji o jijọ ja nkan (ọti) sara, ki nwọn si fikunluku, ki nwọn si ba ara wọn damọran bi alọ ati abọ irinajo na yio ti ṣe dara ti ko ni si rogbodiyan, lẹhin na ki o wa lọ si oju orun Adelaku Adegoke.

Nipa ṣiṣe bayi, awọn wọnpari ẹhanna arijẹninumọdaru alajangbila ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ati Alakukọ yio fi mọ daju gbangba pe ija ti ẹ nja ki iṣe ti gidigbo on alogbe.

Bi Dokita Okpara ba le ṣe ohunti Awa Oniwe Irohin Imọlẹ da ni imọran yi ti ko si kọ eti-ikun si imọran wa na, yio dara pupọ eyi yio si tun fi han pe, ko si kọlọkọlọ ninu kọlọfin isalẹ Ọkan, bi o tilẹ jẹ wipe, awọn mejeji fi itọ pupa sinu nwọn ntu itọ funfun si ita fun araiye ri owe awọn baba wa kan sọ pe, "Ajoji ki i wọlu ki Onile o ma mọ "toto, o sẹ bi owe, ki owe na o si jẹ ti ẹnyin agba.

Ṣugbọn bọya, Ohunti o ya gbogbo enia lẹnu ni wipe lati Ọjọ ti awọn Ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ati Dẹmọ ti nse atotonu yi, Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi ti iṣe Gomina Ipinlẹ na, ko ti sọ Ohunkohun si awọn enia na.

Awa oniwe irohin Imọlẹ wa kesi ọlọla Fadahunsi gẹgẹ bi baba lati kesi awọn enia ẹgbẹ mejeji ni owurọ yi sinu ile rẹ ki o si ba wọn sọrọ ifẹ, Alero pe ọlọla na yio gba Imọran wa yio ba wọn sọrọ pe Ipinlẹ Iwọ Orun pe, ọran ija tabi rogbodiyan ko tun tọ si Ipinlẹ na mọ, agara ti da awọn enia fun ija ojojumọ.

Bakanna ni awa oniwe irohin wa kesi Ọgbẹni Luis Edet Ọga Agba fun gbogbo awọn ọlọpa ẹniti oṣẹṣẹ bosi aye rẹ lẹnulọloyi pe, ko o ṣa gbogbo ohunti o ba wa ni agbara rẹ lati rii wipe awọn ọlọpa ko da omi ata si Dokita Okpara loju ni awujọ enia ninu irinajo rẹ si Ipinlẹ Iwọ Orun.



DỌKITA M. I. OKPARA

Olori Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria

Ipinlẹ na, ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ wipe Okpara gbọdọ lọ si Ipinlẹ na.

Ko tun pẹ pupọ lẹhin yi ti awọn Ọba mejila ni Ipinlẹ Iwọ Orun fi kọwe si Dọkita Okpara ko gbọdọ wa si Ibadan ni asiko yi ki o jẹki o digba miran

Ṣugbọn Dokita Azikiwe, Ogagun gbongbo ti dатọ lẹnu agbin ti fi oke le ọrọ na lara, Okpara si nlọ si Ibadan ni owurọ yi.

LATI OJU EWE KARUN

Balẹ Modakẹkẹ.

Bayi ni itan Modakẹkẹ pari.

Modupẹ lọwọ ẹyin agbagba ti ẹ ṣe wahala nipa itan yi

Ki Oluwa ma jẹki agba ki o tan ni orilẹ lailai.

Mo si dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti nwọn gba mi lati sọ itan yi.

Oluwa ko ni doju ti yin O.

Ẹ ko ni lu ofin Ọlọrun ati t'enia o

O digba kan na o.

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor:— TUNJI ADEOSUN 45, Cambell Street, Lagos ( 2/6/64